| ÀKỌLÉ | Ìtọjú Inú-rere | | |
|---|---|---|---|
| NỌ́ŃBÀ | | **Àtúnṣe tó Kẹ́hìn/Dééti Tí Àyẹ̀wò Bẹ́rẹ̀:** | Ọjọ́ 16 Oṣu kini |
| ÀWỌN IṢẸ́ TJC | LD-FM | | |
| TỌ́KASÍ | | | |

## I. ỌNÀ / ÈRÈDÍ

Ọrọ ìlépa ti Novant Health, "ìmúgbòòrò ìléra àwọn àwùjọ ní ẹlẹ́ni kọọkan nígbà kan" nṣàfihàn àṣà kìí ṣe fún èrè ti Novant Health àti ìjábọ̀ ojúlùmọ̀ ti àwon àwùjọ níbi tí a kalẹ̀ sí.

## II. ÌLÀNÀ ÌṢE

Gbogbo àwọn Ẹ̀ka Novant Health ("Novant Health") yóò pèsè ìtọjú inú-rere (ìtọ́jú ọ̀fẹ́) fún àwọn aláìsàn tó yẹ ṣùgbọ́n tí owó tí o ńwọlé fún wọn kéré. Iṣẹ́ yìí, pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ ànfààní àwujọ mìíràn, ṣe pàtàkì fún ìmúṣẹ ìlépa Novant Health.

Èrèdí ìlànà yìí ni láti ṣagbekalẹ àwọn àmúyẹ àti àwọnàlàkalẹ̀ fún pípésè ìtọjú inú-rere fún àwọn aláìsàn tí ààyè ìṣúná wọn jẹ́ kò ma ṣeeṣe tàbí ma ṣeeṣe láti san owó pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ ìṣègùn tó yẹ. Àwọn iṣẹ́ àṣàyàn kò sí lábẹ́ ìlanà yìí. Àwọn ọlọ́dọnni tí ó bá kójú oṣúwọ̀n àmúyẹ tí a ṣàgbékalẹ̀ nínu ìlànà yìí yẹ láti gba ìtọjú ọ̀fẹ́ fún pàjáwírì tàbí àwọn iṣẹ́ ìṣègùn tó yẹ. Aṣiri iroyin ati iyi ẹnikọ̀ọ̀kan la o dimu fun gbogbo awọn ti o nwa iranwọ labẹ Ilana yii.

Ikọ̀ Aláṣẹ Olùdarí ti Novant Health àti/tàbí Ìgbimọ̀ Àwọn Olùdarí Novant Health gbọ́dọ̀ fi ọwọ́ sí àtúnṣe yóòwù ti ìlànà yìí.

A. <u>Yíyẹ fún Ìtọjú Inú-rere</u>.
   1. <u>Àgbègbè Iṣẹ́</u>
      a. *Ilé-ìwosàn àwọn aláìsàn*:àwọn olùgbé Àgbegbè Iṣẹ́ Novant Health (wo ìsomọ́), yẹ fún ìbéérè fún Ìtọjú Inú-rere, bí a ṣe túmọ̀ rẹ̀ nínu Ìlànà yìí.
      b. *Àgọ́ ìṣegùn tí kìí ṣe olùpesè ("Àgọ́ìṣegùn") àwon aláìsàn:* àwọn aláìsàn gbọ́dọ̀ gbé ní àgbegbè iṣé ìbílẹ̀ fún àgọ́-ìwosàn, gẹ́gẹ́bí àti túmọ̀ àti ṣàkọsílẹ̀ rẹ̀ ní àgọ́-ìwosàn kọ̀kan tí ó sì wà fún bíbéèrè fún aláìsàn.
      c. *Aláìsàn tí a kò dá dúró sílé ìwosàn tí a ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí àìsàn rẹ̀ ní ibi-iṣẹ́ ìtọjú tí kò le ("Aláìsàn tí a kòdá dúró sílé ìwosàn tí a ńlò ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí àìsàn") àwọn aláìsàn:* àwọn aláìsàn tí o ńgbé láyiká bii máìlì márunlelógún sí ibi-iṣẹ́ náà yẹ láti beerè fún Ìtọjú Inú-rere, gẹ́gẹ́bí a ti túmọ̀ nínu Ìlànà yìí.

      Àwọn aláìsàn tí kò sí ní Agbegbè Iṣé Novant Health ni a ó ṣàgbéyẹ́wò tí Àwọn Aàrẹ Ọjà àti/tàbí àwọn àṣojú wọn yóò sì fọwọ́ sí i. Fún ìforukọsílẹ̀ tí a pinnu, láìgba ìfọwọsí tẹ́lẹ̀, a ó retí pé kí àwọn aláìsàn san owó àwon iṣẹ́ tí a ṣe bí aláìsàn náà kò bá gbé ní agbègbè iṣẹ́ Novant Health.
   2. <u>Aláìsàn Tó Fẹsẹmúlẹ̀</u> Ní ti Àgọ́ Oníṣègùn, aláìsàn gbọ́dọ̀ jẹ́ aláìsàn tí a ti tọjú lọ́wọ oníṣègùn ìtọjú àkọbẹ́rẹ̀ ẸgbẹÌṣègùn Novant Health láarin ọdún mẹ́ta (3) sẹ́yìn.
   3. <u>Owó to ń wọlé</u>. Aláìsàn kò gbọdọ̀ ní ètò ìdójútòfò, kó má le rááyé sì àwọn

Ètò Ilaṣẹsi, kí ó má ní owó to ńwọlé tó kere jù tabi jẹ ìlọ́po mẹ́ta ti ọdún lọ́wọ́lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí Àwọn Ìlànà Òṣì Àpapọ̀ kò sì gbọ̀dọ̀ ní owó ohun ìní kankan (bíi owó lọ́wọ́). Ìdábòbò àwọn ẹgbẹ́ tí kò ní ètò ìdójútòfò ní a ó fúnláàárín àwọn àlàfo kan nígbà tí àwọn alákòso bá ṣàyẹwò àti i fún gbogbo àwọn ìwé àkọsílẹ̀ Ìtọjú Inú-rere.

4. Àwọn Iṣé Tóní Ìdábóbò Fún ilé-ìwosàn àti Aláìsàn Oníṣègùn tí o ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí àrùn, lára Àwọn Iṣé tó ní ìdábóbò ni pàjáwírì àti Àwọn Iṣẹ́ Ìṣègùn Tó pọn dandan tí a gbà ní ilé-ìwosàn Novant Health, iṣé tó dá lórí olùpesè, tàbí aatò Aláìsàn Oníṣègùn tí o ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí ààrùn Fún àwọn aláìsàn ti Àgọ́- Oníṣegùn, Àwọn Iṣé Tó ní Ìdábóbò ni ó jẹ́ èyí tí oníṣègùn ṣàgbéyẹ̀wò. Àwọn Iṣé Tó ní Ìdábòbò kò pẹ̀lú ohun ọ̀ṣọ́ ara, yíyàn, àwọn àyẹwò tí kìí ṣe pàjáwírì, àwọn iṣé tàbí ìlanà, àwọn iṣẹ́ agbára ìbímọ tàbí àwọn ìtọjú ìṣayẹwò. Ní ti ipò Àwọn Àgọ́- Oníṣegùn, ìwé ìlànà oogùn kò sí lára Iṣé Ìtí a dáàbòbò.
5. Ìdáàbòbò Ìléra Mîìràn. Àwọn aláìsàn tí a ti mọ̀ pé ó yàn láti máṣe kópa nínu àwọn ètò ìléra ti agbanisíṣẹ́ ṣègbọ̀wọ́ rẹ̀ àti / tàbí tí kò yẹ fún ìdábóbò ìlera ti ìjọba ṣonígbọ̀wọ́ rẹ̀ nítorí àikojú òṣuwọ̀n pẹ̀lú àmúyẹ ètò ni kò yẹ fún Ìtọjú Inú-rere lábẹ Ìlànà yíì. Ìyọkúrò yíì kò kan àwọn aláisàn tí a mọ̀ pé ó yàn láti máṣe kópa nínu àgbékalè ìpààrọ̀ ìtọjú-ìlera tí Ìṣe Ìtọjú Tí Ọwọ́ Ká.
6. Àwọn Ipò Òtò Àwọn aláìsàn tó kú láìni ohun ìní tàbí ìdáàbòbò ẹgbẹ́ kẹta ni a lè gbà fún yíyẹ Ìtọjú Inú-rere. Àwọn aláìsàn tí ó jẹ́ ilé-ìfowopamọ́ nígbèsè náà lè ye fún Ìtọjú Inú-rere.

B. Ìbéèrè - Ìbéèrè (wo ìbéèrè tí a sopọ̀) tó ńpèsè gbogbo àtìlẹ́hìn dátà tí ó yẹ láti jẹ́rì yiyẹ fún Ìtọjú Inú-rere ni aláìsàn náà yóò parí tí yóò dá padà sí ibi-iṣẹ́ okòwò, alágbàwí àkókò ìpawówọlé tàbí àgbaninímọ̀rán ètò ìṣúná owó ní ibi-iṣẹ́ tàbí àgọ́-ìwosàn. Dátà àtìlẹhìn pẹ̀lú ẹ̀rí ti ìwé àkọsílẹ̀ ẹ̀rí bíi àwọn fọ́ọ̀mù W2, ìwé tí a já lára ìsan tàbí ìdápadà owó orí ọdún tókọjá. Àwọn aláìsàn tí kò ní orísun owó to ńwọlé yẹ kí ó kọ lẹ́ta àtìlẹ́hìn tí o ńsọ nípa bí wọ́n ti nílò fún àgbéyẹ́wò Ìtọjú Inú-rere èyí tí ó dá lóri ipò ètò ìṣúná owó wọn lọ́wọ́lọ́wọ́. Ó kéré tán àwọn lẹ́tà gbọ́dọ̀ sọ pé aláìsàn náà kò ní àkọsílẹ̀ ìwé owó àtìlẹhìn láti fi sílẹ̀. Wo Abala G nísàlẹ̀. Àwon ìbéérè ní a ó tọjú níbi-iṣẹ́ tàbí àgọ́-ìwosàn ibi-iṣẹ́ owó tí a ó sì pèsè wọn ẹnikọ́ọ̀kan tí o ńbèèrè Ìtọjú Inú-rere tàbí tí a mọ̀ sí olùwẹgbẹ́ fún Ìtọjú Inú-rere. Àwọn ìbéérè wà ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Sípáníṣì. A lè pèsè ìrànwọ́ ní pípari ìbéérè náà nípa kíkàn sí agbaninímọ̀ràn ètò ìṣúná owó ní èyíkèyí nọ́ńbà fóònù tí a kọ sí Abala O ti Ìlànà yíì.

C. Ìpinnu Tí Ó Dá Lórí Ìbeerè - Ní kété tí a bá ti gbà àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tí a sì ṣe ìpinnu tó yẹ, lẹ́tà ìfitoníletí ni a ó fi ránṣẹ́ sí olùbéérè kọ̀ọkan tí a ó gbà wọ́n níyànjú fún ibi-iṣẹ́ tàbí ìpinnu àgọ́-ìwosàn. Bí aláìsàn náà bá kún ojú òṣùwọ̀n fún àmúyẹ, a ó pe wọ́n ní ẹni tí ó yẹ láti gba Ìtọjú Inú-rere. Àwọn aláìsàn tí o fi àwọn ìbéèrè tí kò pé sílẹ̀ àti/tàbí tí kò pesè ìwé àkọsílẹ̀ àtilẹ́hìn ní a ó bá sọ̀rọ̀ lóri fóònù tàbí méélì.

D. Ìpinnu Àmúyẹ Ìlérò -A lè ṣàyẹwò àṣùwọ̀n owó fún àmúyẹ ìlérò fún Ìtọjú Inú-rere lẹ́hìn ọgọ́fà ọjọ́ àkókò sísan owó bí a kò ba gba ìbéèrè kankan. Àṣùwọ̀n owó yóòwù tí kò ní ìdábòbò ètò ìdójútòfò ní a ó ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ nípa gbígba ìwọ̀n ìdilé àti owó tó wọlé nídilé nípasẹ̀ Ìtọjú-ìwosàn Experian, dátà kan àti àtúpalẹ̀ ilé-iṣẹ́, àti ìṣẹṣirò ìdiwọ̀n Òṣì Àpapọ̀ nínú ọgọ́rún tí ó dá lórí Àwọn Ìlànà ìsisìyí Àṣùwọ̀n owó yòówù lábẹ́ Ìpín Òṣì nínú ọgọ́rún ti Àpapọ̀ tí ó wà lábẹ́ ìlọ́po mẹ́ta tí kò ní ìdábòbò ètò ìdójútòfò yóò yẹ láti gba Ìtọjú Inú-rere yóò si gba àfikún ìlọ́po méjì fún àwọn ìdíyelé àwọn iṣẹ́ ìdábòbò lábẹ Ìlànà yíì.

E. Àwon Olùpesè To Ńpèsè Pàjáwírì àti Ìtọjú Ìṣègún Tó yẹ - Ọ̀kọ̀ọ̀kan ibi-iṣẹ́ NH ńṣàbojutó àtokọ àwon olùpesè tí o ńṣiṣẹ́ pàjáwìrì tàbí ìtọjú ìṣègùn míràn tó yẹ níbi-iṣẹ́ NH, èyí to ń ṣàfihàn àwọn olùpesè wo ló wà lábẹ Ìlànà yíì ("Àtokọ ti Àwọn Olùpesè"). Àtokọ yíì ni a lè ṣàfikún ní orèkoorè láìgba àṣẹ ìgbimọ aláṣẹ ibi-iṣẹ́ NH. Àtokọ Àwọn Olùpesè ni a lè gbà nípasẹ ojú-òpó ayé-lu-jára Novant Health tàbí kíkànsí agbaninimọ́ràn ètò ìṣúná owó ní èyíkèyí àwọn nọ́ńbà fóónù tí a kọ sí Abala O ti Ìlànà yíì.

F. Àkókò Àmúyẹ - Ìbéèrè Ìtọjú Inú-rere náà àti àkọsílẹ̀ ìwé ni a gbọ́dọ̀ sọ dọ̀tun ní oṣú mẹ́fà-mẹ́fà, tàbí nígbàkugbà láàrín sáà oṣù mẹ́fà tí owó to ń wọlé fún ẹbí aláìsàn tàbí àyípadà ipò ètò ìdójútòfò títí dé ààyè tí aláìsàn náà kò fi yẹ. Àbẹwò kọọkan láàrín sáà oṣù mẹ́fà náà ni a ó gbè yẹ́wò fún ìraayesí fún Àwọn Etò Yíyẹ mìíràn.

G. Kò sí Àtìlẹ́hìn Àkọsílẹ̀ Ìwé Owó - Àwọn aláìsàn tí kòní orísun owó to ńwọlé ni a lè kàsí inú-rere bí wọn kò ba ní iṣẹ́, àdírẹ́sì méélì, ìbùgbé tàbí ètò ìdójútòfò. Ìpinnutún gbọ́dọ̀ wáyé fún àwọn aláìsàn tí kò pesè ìròyìn tó yẹ nípa ipò ètò ìṣúná owó wọn. Àwon aláìsàn tí kò ní orísun owó to ńwọlé gbọ́dọ̀ pesè lẹ́tà àtìlẹ́hìn tí ó nsọ nípa àìní wọn fún Ìtọjú Inú-rere ní ìpinnu tó dá lórí ipò ètò ìṣúná owó wọn lọ́wọ́lọ́wọ́. Ó kéré tán àwọn lẹ́tà gbọ́dọ̀ sọ pé aláìsàn náà kò ní àkọsílẹ̀ ìwé owó àtìlẹ́hìn láti fisílẹ̀. Ìtọjú Inú-rere ní a lé mà fi duni lábẹ Ìlànà yíì nítorí ìkunà olùbéérè láti pèsè ìròyìn tàbí àkọsílẹ̀ ìwé ti Ìlànà yíì tàbí fọ́ọ́mù ìbéérè tí wọn kò nílò kí ẹnìkan fi sílẹ̀.

H. Àwọn Ìṣe Sísan owó àti Gbígbà - Fún ìròyìn nípa àwọn iṣé sísan owó àti gbígbà Novant Health jọ̀wọ́ wo Ìlànà Sísan owó àti Gbígbà Novant Health. Ẹ̀dà ti ìlànà náà ni a lè gbà ní ojú-òpó ayé-lu-jára Novant Health tàbí nípa kíkànsí agbaninímọ̀rán ètò ìṣúná owó kan ní àwọn nọ́ńbà fóònù tí a ṣe àtokọ rẹ̀ ní Abala O ti Ìlànà yíì.

I. Déètì tí Ìtọjú Inú-rere Bẹ̀rẹ̀. Bí o ti dára láti pinnu yíyẹ fún Ìtọjú Inú-rere aláìsàn bí o ti súnmọ́ àkókò iṣẹ́ tó, níwọ̀n ìgbà tí aláìsàn náà bá fi ìwé àkọsílẹ̀ tí ó yẹ sílẹ̀ láarín Àkókò Ìbéèrè, a ó pesè Ìtọjú Inú-rere.

J. Ìtọjú Àkọsilẹ̀ -Àwọn àkọsílẹ̀ tí ó jẹmọ́ Ìtọjú Inú-rere àwọn aláìsàn tí o ńbọ̀ ni a gbọ́dọ̀ gbà fún lílò. Àwọn àwòrán àkọsílẹ̀ ìwé tí ó jẹmọ́ Ìtọjú Inú-rere ni a lè ráàyè sí ní àwọn agbègbè yìí ní àkọ́ọ̀lẹ̀ tàbí ìpele àkọ́ọ̀lẹ̀ ìṣègùn ti aláìsàn náà fún mímú jáde:

- Àṣedúró Yíyí NHMG: Ìwé àkọsílẹ̀ ìbéérè ni a fi pamọ́ sínu àpotí ìpamọ́ fáìlì fún ọ̀gbọ̀n ọjọ́ a sì ṣẹ̀dà àwòrán ní Hyland OnBase fún ìpamọ́.
- Àwọn Ibi-iṣẹ́ Aláìsàn to ńgbalé wá tí o ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí àrùn: Àwọn ìwé àkọsílẹ̀ ni a ṣẹ̀dà àwòrán wọn sínú ètò ìṣakósò láàrín Centricity fún ìtọjú.
- Àwon ibi-iṣé Lílé ti Àfibọ̀: Àwọn ìwé àkọsílẹ̀ ni a ṣẹ̀dà àwòrán wọn sínú ètò Siemens EDM fún ìtọjú
- Àwon ibi-iṣé Lílé ti Ọ̀diwọ̀n: Àwọn ìwé àkọsílẹ̀ ni a ṣẹ̀dà àwòrán sínú alákòso mídíà fún ìtọjú.

K. Ìdíyelé. Kò sí ẹni tí ó yẹ fún Itọjú Inú-rere tí a ó gba ìdíyelé lọ́wọ́ rẹ̀ fún pàjáwìrì tàbí ìtọjú ìṣègùn mìíràn tó ṣe pàtàkì lábẹ Ìlànà yíì. Bí Novant Health bá fẹ́ gba ìdíyelé

fún pàjáwírì tàbí ìtọjú ìṣègùn mìíràn tó yẹ lábẹ Ìlànà yíì, yóò lo ọ̀nà ìfojusọ́nà láti pinnu iye owó tí a bù fúnni lápapọ̀ ní lílò iye Medicaid ("AGB") àti pé kò níí ṣe ìdíyelé ẹnìkọọkan tí ó yẹ fún Ìtọjú Inú-rere sì ju AGB lọ.

L. Ìṣuná owó Ìtọjú Inú-rere. Wíwá Ìtọjú Inú-rere lè dínkù lóri ìṣuná owó Novant Health tàbí àwọn ìdiwọ́ owó míìràn, èyí tí yóò nípa lóri ipá ti Novant Health láti lè lẹ́sẹ̀ nílẹ̀ ní ti owó.

M. Àkíyèsí Àwùjọ àti Ìfọ̀rọ̀ránṣẹ́ - Novant Health yóò pèsè ìròyìn fún awùjọ nípa ìrànwọ́ tí a npèsè nínu Ìlànà yíì báyìí:

- Ìlànà yíì, ìbéérè àti Ìṣọníṣokí Èdè Ketekete yóò wà ní ojú-òpó ayé-lu-jára NH;
- Àwọn ẹ̀dà ìwé ti Ìlànà yíì, ìbéérè àti Ìṣọníṣokí Èdè Ketekete ni a ò pesè bí a bá béèrè fún u àti láìní ìdíyelé, nípa méélì àti ní àwọn ibi àwujọ káàkiri ibi-iṣẹ́ Novant Health, àti ní ẹ̀dinwó ER àti àwọn agbègbè ìgbaniwọlé;
- Àwọn pánfúlẹ́tì ìtọjú inú-rere, èyí to sọ fún olùkàwé nípa ìrànwọ́ owó tó wà lábẹ́ Ìlànà yíì, ọ̀nà láti gba ìròyìn sí i nípa Ìlànà yíì àti ìgbésẹ̀ ìbéérè, àti bí a tì le gba àwọn ẹ̀dà Ìlànà yíì, ìbéèrè náà àti Ìṣoniṣókí Èdè Ketekete, yóò wà ní onírúurú àwùjọ àgọ́-ìwòsaǹ ìlera lọ́fẹ̀ẹ́ láàrín Agbègbè Iṣẹ́ Novant Health;
- Àwọn aláìsàn ni a ó fún ní ẹ̀dá ìwé ti Ìṣoniṣókí Èdè Ketekete gẹ́gẹ́ bí ara ètò jíjẹ tàbí títì síta;
- Àwọn gbólóhùn owó-sísan yóò ní àfiyèsí tó hàn gedegbe nípa wọn láti sọ fún olùkàwé nípa Ìlànà yíì, bí a ti kọ síwajú sí i lẹ́kunrẹ́rẹ́ nínu Owó-Sísan àti owó-gbígbà ti Novant Health; àti
- Ìṣafihàn àwùjọ ketekete tó npè àkíyèsí àti wífún àwọn aláìsàn nípa Ìlànà yíì ni a ó ṣàfihàn ní àwọn ibi gbangba káàkiri ibi-iṣé Novant Health, pẹ̀lú ní ẹ̀dinwó kékeré ER àti agbègbè ìgbaniwọlé.

N. Ìwọlé Ẹnìkọọkan si LEP - Novant Health yóò jẹ́ kí Ìlànà yíì, fọ́ọ̀mù fún ìbéèrè náà àti Ìṣoniṣókí Èdè Ketekete wà ní àrọ́wọ́tó fún àjọ àwọn ènìyàn tó lápẹẹrẹ tí kò ní òye èdè Gẹ̀ẹ́sì púpọ̀ ("LEP"). Láti pinnu bóyá àjọ àwọn ènìyàn kan jọjú, Novant Health yóò lo ọ̀nà tó nítumọ̀ láti pinnu èdè àwọn ẹgbẹ́ LEP láàrin Àgbègbè Iṣẹ́ Novant Health.

O. Wíwá ti Ìlànà àti Ìwé Àkọ́sílẹ̀ Tó jọra. Fún àwọn aláìsàn ilé-ìwòsàn, ẹ̀dà Ìlànà yíì kan, Ìṣọníṣókí Èdè Ketekete, ìbéèrè kan, Àtokọ àwọn Olùpesè àti Ìlànà Ìsan Owó àti Gbígbà ni a lè gbà nípasẹ̀:

- Ìbẹ̀wò sí ojú-òpó ayé-lu-jára Novant Health ni **http://www.novahealth.org/GiveBack/FinancialAssistance.aspx**
- Ṣíṣe ibẹwò sí ibi-iṣẹ́ Ìgbaninímọ̀ràn Owó ní èyíkèyí ilé-ìwosàn Novant Health.
- Pípe ìpè-ọ̀fẹ́ sí Iṣẹ́ Oníbàárà ni 888-844-0080
- Pípe èyíkèyí olùgbàninímọ̀ràn owó ilé-ìwosàn Novant Health ní àwọn nọ́ńbà àtokọ ìsalẹ̀:

| | |
|---|---|
| Novant Health Forsyth Medical Center<br>Novant Health Clemmons Medical Center<br>Novant Health Kernersville Medical Center<br>Novant Health Medical Park Hospital<br>Novant Health Thomasville Medical Center<br>Novant Health Rowan Medical Center | (336) 718-5393 |
| Novant Health Presbyterian Medical Center<br>Novant Health Matthews Medical Center<br>Novant Health Huntersville Medical Center<br>Novant Health Charlotte Orthopedic Hospital<br>Novant Health Brunswick Medical Center | (704) 384-0539 |
| Novant Health Prince William Medical Center<br>Novant Health Heathcote Medical Center<br>Novant Health Haymarket Medical Center | (703) 369-8020 |

Fún àwọn àgọ́- Onísègùn àti Ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí àrùn  ti Aláìsàn to ńgba ilé wá, ẹ̀dà ìlànà ti ìtọjú inú-rere kan, ìsọníṣókí èdè ketekete, ìbéèrè kan àti ìlànà owó-sísan àti gbígbà ni a lè rí gbà nípa kíkànsí àgọ́-ìwosàn náà.

**ÀWỌN ÌYỌKÚRÒ**: Ìlànà yíì  kan àwọn iṣẹ́ tí a ṣe ní àwọn alábàáṣepọ̀ Novant Health nìkankó sì kan àwọn iṣé tí a ṣe lọ́dọ̀ àwọn oníṣègùn tàbí ọ̀jọ̀gbọ́n tí ó dá dúró.  Ìlànà yíì bákàn náá kò kan àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ṣe láàrín tàbí níta ilé-ìwosàn/ibi-iṣẹ́ láti ọ́wọ àwọn oníṣègùn tàbí àwọn olùpesè ìtọjú-ìlera míìràn ṣùgbọ́n kò parí sọ́dọ̀  àwọn Oníṣègùn Akunnilórun, Oníṣègùn tí o ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí ààrùn , àti/tàbí Oníṣègùn tó ṣàwarí òkunfà àti ìdàgbà aarùn.

## III. ÒṢÌṢẸ́ AKỌ́ṢẸ-MỌṢẸ́

N/A

## IV. IRIN IṢẸ́

N/A

## V. ÌLÀNÀ

*Ìlànà náà wà gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ni láti ran òṣiṣẹ́ lọ́wọ́ ní dídé àwọn ìlépa ti ìlanà iṣé náà. Níwọ̀n ìgbà tí  títẹ̀lé àwọn ìlànà ìtọ́ni òṣìṣẹ́ ní a   yóò lè ṣe ìdajọ́ ní ìbámu pẹ̀lú gùngun iṣé àti/tàbí ojúṣe iṣẹ́.*

N/A

## VI. ÀKỌSÍLẸ̀

N/A

## VII. ÀWỌN ÌTUMỌ̀

**Alábàáṣepọ̀ –** pẹ̀lú Novant Health, Inc. àti gbogbo ohun aládàni tàbí ohun tí nṣiṣẹ́ lábẹ orúkọ Novant Health.

**Àkókò Ìbéèrè –** àkókò tí o bẹ̀rẹ̀ ni déètì tí a ṣe ìtọjú náà fún olúkúlúkù tí o sì nparí  lẹ́hìn ojìlélúgba ọjọ́ lẹ́hìn tí a ti pesè fún olúkúlúkù pẹ̀lú ọ̀rọ̀ owó -sísan fún ìtọjú náà.

**Ìtọjú Inú-rere** – Àwọn iṣẹ́ to nílò láti tọ́jú àìlera, ìpalara, ipò, aarùn, tàbí àwọn aamì rẹ̀ àti èyí tí ó bá gbèndéke àtẹwọ́gbà lọ tiìṣègùn mu, èyí, tí wọ́n kò bá tọ́jú kíákíá, yóò jásí ipò ìlera tí ó léwu.

**Ètò Ìlẹ́tọsí –** ètò ìjọba tó nfúnni ní ìdanilójú àwọn ànfàání ìtọjú ìlera kan fún àwọn ìpele ènìyàn kan.  Èyí kò kan àgbékalẹ̀ pàṣípàrọ̀ ìtọjú-ìlera ti Iṣé Ìtọjú Tí Ọwọ́ Ká.

**Ẹbí** – Ninu wọn ni ọkọ, ìyàwó, àti àwọn ọmọ yóòwú (pẹ̀lú àwọn ọmọ-ọkọ\ìyàwói) tí o ń gbé nínu ilé náà tí o sì yẹ fún gbígba àwọn erèdí owó orí.

**Owó to ńwọlé** – Owó tí ẹbí ńpa wọlé lọ́dún àti àwọn ànfàání owó láti gbogbo orísun ṣáajú àwọn owó orí, àìsantó owó fún owó ìtọjú obìrin tí a kọ sílẹ̀ àti àtìlẹ́hìn ọmọ.

**Ó Ṣe Pàtàkì Ni Ti Ìṣègùn Àwọn Iṣẹ́** – Àwọn iṣẹ́ fún ipò èyí, tí wọn kò bá tọ́jú kíákíá, yóò jásí ipò ìlera tí ó léwu.

**Ìsọníṣokí Èdè Ketekete** – Ohun tí a kọ sílẹ̀ tí o ńpè àkíyèsí ẹnikọ̀ọ̀kan sí pe ibi-iṣẹ́ Novant Health ń pèsè ìrànwọ́ owó lábẹ Ìlànà yìí ti ó sì npèsè àwọn ìròyìn àfikún yíì ní èdè tí ó já geere, ṣókí, ti ó sì rorùn láti yéni: (i) ìsọniṣókí àpejúwè  ti àmúyẹ fún ìbámu àti ìrànwọ́ tí a  fúnni lábẹ Ìlanà yii; (ii) ìsọníṣókí bí a ti ńbèèrè fún ìrànwọ lábẹ Ìlànà yii; (iii) àdírẹ̀sì ojú-òpó ayé-lu-jára taarà (tàbí URL) àti ibi ìkalẹsì níbi tí ènìyàn ti lè gba àwọn ẹ̀dà  Ìlanà yii ati fọọmu ibeere; (iv) àwọn ìtọ́ni bí oníkálukú ṣe le gba ẹ̀dà  Ìlanà yìí  àti fọ̀ọ̀mù ìbéérè lọ́fẹ̀ẹ́; (v) àlàyé ìkansí, pẹ̀lú nọ́ńbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti ibi ìkalẹ̀sí, ti ibi iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka tí o lè pesè àlàyé nípa Ìlanà yìí àti bóyá ibi-iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka tí o lè pesè ìranwọ́ fún ìbéérè tàbí ibi-iṣẹ́ tí kìíṣe fún èrè tàbí alágbàṣe ìjọba tí ó lè pèsè ìrànwọ́; (vi) àlàyé lóri wíwá àwon ìtumọ̀ Ìlanàyìí, ìbéérè àti Ìsọníṣókí Èdè Kétekète ní àwọn èdè míìràn, bí ó bá yẹ, àti (vii) àlàyé pé ẹni tí ó yẹ fún Ìtọjú Inú-rere ni lè má san iye owó tí àwọn tí ó níètò ìdúrótòfò ńsan tí ó ní ìtọjú pàjáwìrì kan náà tàbí ìtọjú ìṣègún míìrán tí ó yẹ.

**Agbègbè Iṣẹ́ Ìbílẹ̀** –  Tí a túnmọ̀ àti ti Àgọ̀ Oníṣègùn  tó yẹ ńlò lórèkoorè àti pẹ̀lú àwọn aláìsàn ìdá méjọ sí mẹ́sán ninú mẹ́wàá wọn.

## VIII. ÀWỌN ÌWÉ  TÍ Ó JỌRA WỌN

Ìyanjú Ìjàmbá; Ẹ̀dínwó Àìní-ìdábòbò; Ìlanà Sísanwó; Ìgbaniwọlé; Àwọn sísan àti Ìmọ̀ràn Owó, Iṣan owó àti àwọn Gbígbà

## IX. ÀWỌN ÌTỌ́KASÍ

N/A

## X. ÌFÍSÍLẸ̀ LÁTI ỌWỌ́

Itọju Inu-rere Novant Health/ Ìgbimọ̀ Alábẹ̀ṣékélé fún Gbèsè tí a kò ri Gbà

## XI. ÀWỌN KÓKÓ ỌRỌ

Inú-rere, aláìsàn tí kòní ìdójútòfò, ìtọjú inú-rere, ìrànwọ owó

## XII.

| | |
|---|---|
| **DÉÈTÌ TÍ O KỌKỌ BẸẸRẸ** | Ọjọ kinni oṣù kẹfà, ọdún 2015 |
| **DÉÈTÌ TÍ ÀWỌN ÀTÚNṢE BẸRẸ** | 01/2016 |
| **DÉÈTÌ ÀTÚYẸWÒ (Kò sí àyípàdà)** | |
| **Déètì Tí ó Tún Yẹ fún Àtúnyẹwò** | Osù kinní ọdún 2019 |

## ÌWÉ ÌBỌWỌ́LÙ

| | |
|---|---|
| **ÀKỌLÉ** | Ìtọjú Inú-rere |
| **NỌ́ŃBÀ** | |
| **ÀWỌN IṢÉ TJC** | LD-FM |
| **TỌ́KASÍ** | |
| **ÌṢE** | Tí a yẹwò |

**TÍ A FỌWỌSÍ NÍPASẸ̀:**

| Àkọlé | Tí a fọwọsí Nípasẹ̀ | Ìbọwọ́lù | Déètì |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |

**ÌÀWỌN ÌGBIMỌ̀ TÍ A FỌWỌ́SÍ NÍPASẸ̀:**

| Ìgbimọ̀ | Alága/Aṣojú | Déètì |
|---|---|---|
| | | |
| | | |

## NC àti Agbègbè iṣẹ́ SC




## Agbègbè Iṣẹ́ Àriwá VA



# Ìbéèrè Ìrànwọ́ Owó

## I. Àwọn Ìjúwe Aláìsàn

Orúkọ Aláìsàn: ______________________________________________
(Ìkẹhìn) (Àkọkọ́) (Aarín) (SSN) (DOB)

OrúkọOnígbọ̀wọ́:______________________________________________
(Ìkẹhìn) (Àkọkọ́) (Aarín) (SSN) (DOB)

Àdírẹ́sì: ______________________________________________
(Òpopó) (Ìlú) (Ìpínlẹ̀) (Kóòdù Síípù)

Fóònù:________________________

## II. Ìròyìn Ìdilé

| **Ipò Ìgbéyàwó** *(Kálé Mọ̀ Ọ̀kan)* | **Ó Ti Gbéyàwó** | **Àpọn** | **Wọ́n Ti Pínyà** | **Àpapò Iye ní Ìdilé** |
|---|---|---|---|---|

| **Orúkọ Ìbátan ẹni**(*So ìwé pélébé ọ̀tọ̀ mọ ọ fún àfikún Ìbátan ẹni)* | **Ọjọ́ ìbí Ìbátan ẹni** |
|---|---|
| | |
| | |
| | |

## III. Iṣẹ́/Owó tó ń wọlé

| |
|---|
| **Aláìsàn/Agbanisiṣẹ Onígbọ̀wọ́:** |
| **Iye Owó To Ńwọlé Lóṣù Lápapọ̀: $** |
| **Orísun Owó to ń wọlé -***Jọ̀wọ́ ṣàsopọ̀ ìjẹ́rì tàbí àlàyé ipò lọ́wọ́lọ́wọ́* |
| **Orísun Owó Mìírán to ńwọlé àti Iye Owó To Ńwọlé Lóṣù Lápapọ̀: $** |
| **Àpapọ̀ Owó Ìdilé Tó Ńwọlé Lọ́dọọdún: $** |

## IV. Ìṣèjẹ́rì Ètò Ìdójútòfò

| **Ṣé o ní èyíkèyìí ìdójútòfò ìlera?** | **BẸ́Ẹ̀NI** | **BẸ̀Ẹ̀KỌ́** |
|---|---|---|
| **Bí bẹ́ẹ̀ni, jọ̀wọ́ ṣàlàyé:**<br>*(m orúkọ, àdírẹ́sì, nọ́ńbà fóònù, ìlànà/nọmba ẹgbẹ́ àti ìròyìn ọmọ ẹgbẹ́ ilé-iṣẹ́ adójútòfò pẹ̀lú rẹ̀)* | | |
| **Ṣé o nìṣẹ́ lọ́wọ́?** | **BẸ́Ẹ̀NI** | **BẸ̀Ẹ̀KỌ́** |
| **Bí Bẹ́ẹ̀ni, kọ àtòkọ ìròyìn agbanisíṣẹ́ lọ́wọ́lọ́wọ́:** | | |
| **Bí Bẹ̀ẹ̀kọ́, kọ àtòkọ ìròyìn agbanisíṣẹ́ tó kọjá (pẹ̀lú àwọn déètì):** | | |

*Mo jẹ́rì pé ìròyìn tí mo pèsè jẹ́ òtitọ́ àti fún ìmoye mi jùlọ. Mo lóye pé ìròyìn jìbìtì tàbí ìṣinilọ́nà yóò mú mi jẹ́ aláìyẹ fún ìrànwọ́ owo kankan. Mo fàáye gbà ìfisílẹ̀ ìròyìn yòówù tí a nílò láti jẹ́rì ìròyìn tí mo pesè àti fún sísan owó àti gbígba ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìjọba àpapọ̀ àti ti ìpínlẹ̀. A lè béèrè fún ẹ̀rí owó to ńwọlé ṣáajú kí a tó ṣàgbéyẹ̀wò kankan. Ẹ̀rí owó to ńwọlé tí ó ṣe ìtẹ́wọ́gbà bóyá ṣùgbọ́n tí kò pin sí: ẹ̀dà ìwé tí a ya lára ìwé sọ̀wédowó, ẹ̀dà ẹ̀rí owó orí sísan ti ọdún tó kọjá, tàbí lẹ́tà láti ọ̀dọ̀ agbanisíṣẹ́ tí ó nsọ nípa owó oṣù lọ́wọ́lọ́wọ́ àti wákàtí iṣẹ́.*

| ***Ìbọwọ́lù Aláìsàn/ Onígbọ̀wọ́*** | | ***Déètì:*** |
|---|---|---|
| Ìbọwọ́lù Afọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò | | Déètì: |
| Ìbọwọ́lù Alábòjútó | | Déètì: |
| Ìbọwọ́lù Adarí | | Déètì: |
| Ìbọwọ́lù ti SVP | | Déètì: |
| Àwon Àsọyé | | |

# Notice of nondiscrimination

Novant Health complies with applicable Federal civil rights laws and does not discriminate on the basis of race, color, national origin, age, disability, or sex. Novant Health does not exclude people or treat them differently because of race, color, national origin, age, disability, or sex.

Novant Health:

- Provides free aids and services to people with disabilities to communicate effectively with us, such as:
  - Qualified sign language interpreters
  - Written information in other formats (large print, audio, accessible electronic formats, other formats)
- Provides free language services to people whose primary language is not English, such as:
  - Qualified interpreters
  - Information written in other languages

**If you need these services, please contact Novant Health interpreter services toll-free at 1-855-526-4411, then select option 3. TDD/TTY: 1-800-735-8262.**

If you believe that Novant Health has not provided these services or discriminated in another way on the basis of race, color, national origin, age, disability, or sex, you can file a grievance with:

Patient services department
Attn: Section 1557 coordinator
200 Hawthorne Lane
Charlotte, NC 28204

Telephone: 1-888-648-7999 (toll-free)
TDD/TTY: 1-800-735-8262
**NovantHealth.org/home/contact-us.aspx**

You may file a grievance by mail, in person at the Novant Health facility where care was provided, or by submitting the form at the link above. If you need help filing a grievance, call toll-free, 1-888-648-7999 or TDD/TTY 1-800-735-8262.

You may also file a civil rights complaint with the U.S. Department of Health and Human Services, Office for Civil Rights, electronically through the Office for Civil Rights Complaint Portal, available online at **ocrportal.hhs.gov/ocr/portal/lobby.jsf**, or by mail or phone at:

U.S. Department of Health and Human Services
200 Independence Avenue, SW
Room 509F, HHH Building
Washington, D.C. 20201
1-800-368-1019, 800-537-7697 (TDD)
Complaint forms are available at **hhs.gov/ocr/office/file/index.html**

***ATTENTION*****: Language assistance services, free of charge, are available to you. Call 1-855-526-4411. Select option 3. TDD/TTY: 1-800-735-8262.**

NOVANT HEALTH

# Notice of nondiscrimination

| | |
|---|---|
| Español (Spanish) | *ATENCIÓN: Los servicios de asistencia lingüísticos, gratuitos, están disponibles para usted. Llame al 1-855-526-4411. Seleccione la opción 3. TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| 繁體中文 (Chinese) | *注意： 您可以享受免費的語言協助服務。請撥打1-855-526-4411。選擇選項3。TDD/TTY：1-800-735-8262。* |
| Tiếng Việt (Vietnamese) | *CHÚ Ý: Có các dịch vụ hỗ trợ ngôn ngữ miễn phí dành cho quý vị. Gọi 1-855-526-4411. Chọn tùy chọn 3. TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| 한국어 (Korean) | *주의: 무료 언어 지원 서비스를 이용하실 수 있습니다. 1-855-526-4411번으로 전화하십시오. 옵션 3을 선택하십시오. TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| Français (French) | *IMPORTANT : Des services d’assistance linguistique gratuits sont à votre disposition. Appelez le +1 855 526 4411. Sélectionnez l’option 3. Dispositif de télécommunication pour sourds et malentendants : +1 800 735 8262.* |
| ال عرب ية (Arabic) | *ملاحظة: خدمات المساعدة اللغوية المجانية متاحة لك. اتصل على الرقم 1-855-526-4411. اختر الخيار 3. جهاز الاتصال الكتابي/الهاتف النصي: 1-800-735-8262.* |
| Русский (Russian) | *ВНИМАНИЕ: Для вас доступна бесплатная услуга языковой поддержки. Позвоните по телефону 1-855-526-4411. Выберите вариант 3. Текстовый телефон/телетайп: 1-800-735-8262.* |
| Tagalog (Tagalog – Filipino) | *ATENSYON: May mga libreng serbisyo ng tulong sa wika na available sa iyo. Tumawag sa 1-855-526-4411. Piliin ang opsyon 3. TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| ف ار سی (Farsi) | *توجه: خدمات ترجمه به طور رایگان در اختیارتان قرار دارد. با شماره 1-855-526-4411 تماس بگیرند. گزینه 3 را انتخاب کنید. TDD/TTY :1-800-735-8262* |
| አማርኛ (Amharic) | *ማሳሰቢያ፦ የቋንቋ እርዳታ አገልግሎቶች በነጻ ይገኛሉ። በ 1-855-526-4411 ላይ ይደውሉ። አማራጭ 3ን ይምረጡ። TDD/TTY፦ 1-800-735-8262.* |
| Deutsch (German) | *HINWEIS: Es stehen Ihnen kostenlose Sprachassistenzdienste zur Verfügung. Wählen Sie +1 855 526 4411. Wählen Sie Option 3 aus. TDD/TTY: 1 800 735 8262.* |
| اُردُو (Urdu) | *برائے توجہ: آپ کے لیے زبان سے متعلق اعانت کی خدمات، مفت دستیاب ہیں۔ 1-855-526-4411 پر فون کریں۔ اختیار 3 چنیں۔ TDD/TTY: 1-800-735-8262۔* |
| हिंदी (Hindi) | *ध्यान दें: आपके लिए निःशुल्क भाषा सहायता सेवाएं उपलब्ध हैं। 1-855-526-4411 को कॉल करें। विकल्प 3 चुनें। TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| ગુજરાતી (Gujarati) | *સાવધાન: તમારા માટે ભાષા સહાય સેવાઓ, વિના મૂલ્યે, ઉપલબ્ધ છે. 1-855-526-4411 પર કૉલ કરો. વિકલ્પ 3 પસંદ કરો. TDD/TTY: 1-800-735-8262.* |
| বাংলা (Bengali) | *মনোযোগ দিন: আপনার জন্য বিনামূল্যে ভাষা সহায়তা পরিষেবা লভ্য আছে। 1-855-526-4411 নম্বরে ফোন করুন। বিকল্প 3 নির্বাচন করুন। TDD/TTY: 1-800-735-8262।* |